# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OṢÙ KEJE, ỌDÚN 2022**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**(Ìsìn Omi Iná)**

## OṢÙ KEJE 2022 - DÍDÒJÚKỌ ÀWỌN Ẹ̀MÍ ÒKÙNKÙN ÀJÀKÁLẸ̀-ÀRÙN TÓKÁRÍ AYÉ (5)

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8:45 am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

## MO KẸ́SẸ̀ MI LÉ JÉSÙ

1. Mo kẹ́sẹ̀ mi lé Jésù,
Ọ̀dágùntàn mímọ́,
Ó ru gbogbo ẹ̀rù mi,
Ó sọ mí d'omìnìra,
Mo ru ẹ̀bi mi tọ̀ wá,
K'Ó wẹ èrí mi nù,
K'ẹ́jẹ̀ Rẹ iyebíye,
Lè sọ mí di mímọ́.

2. Mo k'áìnì mi lé Jésù,
Tìrẹ l'ohun gbogbo;
Ó w'àrùn mi gbogbo sàn,
Ó r'ẹ̀mí mi padà,
Mo kó ibànújẹ́ mi,
Ẹ̀rù at'àníyàn,
Lé Jésù, Ó sì gbà mí,
Ó gba ìrora mi.

3. Mo gbọ́kàn mi lé Jésù,
Ọkàn arè mì yí;
Ọw'ọ́tùn Rẹ gbá mi mú,
Mo simi l'áyà Rẹ.
Mo fẹ́ orúkọ Jésù,
Ìmánúẹ́lì, Kríst'Olúwa;
Bí òrún dídùn yíká,
Ní orúkọ Rẹ jẹ́.

4. Mo fẹ́ kí nrí bí Jésù,
Ní rẹ̀lẹ̀ at'ìfẹ́;
Mo fẹ́ kí nrí bí Jésù,
Ọmọ mímọ́ Bàbá;
Mo fẹ́ kí mbá Jésù gbé,
Láràn ẹgbẹ́ mímọ́,
Kí nkọrin ìyìn títí,
Orin t'ángẹ́lì nkọ.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Pẹpẹ ibi ìyówù, tí wọ́n yàn láti mú ògo ayànmọ́ mí lẹ́rú, ìwọ iná Ọlọ́run, bọ́lù ú báyìí, kí ò sì jó di éérú, ní orúkọ Jésù.
2. Bàbá mi, nínú ètò tòní, rán agbára Rẹ láti túmisílẹ̀ kúró lọ́wọ́ gbogbo agbára tó de ògo mi mọ́lẹ̀, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo pẹpẹ ibi tówà nídi àwọn ogun nínú ayé mi, òní ni òpin iṣẹ́ rẹ, gbiná báyìí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ẹ̀bùn ibi nínú ohun ìní mi, tí wọ́n n lò láti fi darí ayé mi, òní lo ráyé mọ, gbiná, ní orúkọ Jésù.

5. Gbogbo àgbà ìkà ilé bàbá mi, iṣẹ́-ìránṣẹ́ rẹ lórí ayé mi yóò dópin lónì, dá ara rẹ lóró, ki o sì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn ogun àjogúnbá ibi, látòní lọ, èmi kì íṣe ìjẹ rẹ mọ́, nítorí náà, túmisílẹ̀, ki o sì kú, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run dìde, bẹ̀ mí wò lónì, kí o sì gbé ayànmọ́ mi láti ibi kékeré lọ síbi tó tóbi, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run dìde, gbà mí kúrò lọ́wọ́ ogun tó n wí pé òhun yóò rẹ́yìn mi, ní orúkọ Jésù.
4. Rìkiṣí ìkà ìkọ̀kọ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi, ta padà, ní orúkọ Jésù.
5. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí àwọn ohun ìjà ọ̀tá yípadà lòdì sì i, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ìránṣẹ́ ìkùnà nínú ayànmọ́ mi, já ìdè rẹ, ki o sì kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ìránṣẹ́ ibi ìkọ̀kọ̀, tó wà lójú iṣẹ́ lòdì sí ayé mi, pa ara rẹ run, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Deuterónómì 20:4:** Nítorípé OLÚWA Ọlọ́run nyín ní mbá nyín lọ, láti bá àwọn ọ̀tá nyín jà fún nyín, láti gbà nyín là.

**Isàíàh 41:13:** Nítorí èmi Olúwa Ọlọ́run rẹ yóò di ọwọ́ ọ̀tún rẹ mú, èmi ó wì fún ọ pé, Má bẹ̀rù; èmi ó ràn ọ́ lọ́wọ́.

**Orin Dáfídì 108:13:** Nípaṣẹ̀ Ọlọ́run li àwa ó ṣe akin; nítorí Òun ni yóò tẹ àwọn ọ̀tá wa mọ́lẹ̀.

**Òwe 24:16:** Nítorí olótọ́ á ṣubú nígbà méje, á sì tún dìde: ṣùgbọ́n ènìyàn búburú yóò ṣubú sínú ibi.

**Jósúà 10:8:** OLÚWA sì wí fún Jóṣúà pé, Má ṣe bẹ̀rù wọn: nítorítí mo ti fi wọ́n lé ọ lọ́wọ́; kì yóò sí ọkùnrin kan nínú wọn tí yóò lè dúró níwájú rẹ.

**Òwe 3:5-8:** Fí gbogbo àyà rẹ gbẹ́kẹ̀lẹ́ Olúwa; má sì ṣe tẹ̀ sí ìmọ̀ ara rẹ. Mọ̀ ọ́ ní gbogbo ọ̀nà rẹ: òn ó sì ma tọ́ ipa-ọ̀nà rẹ. Máṣe ọlọ́gbọ́n lí ojú ara rẹ; bẹ̀rù Olúwa, kí o sì kúrò nínú ibi. Òn ó ṣe ìlera sí ìdodo rẹ, àti ìtura sí egungun rẹ.

**Málákì 4:2:** Ṣùgbọ́n Òrùn òdodo yóò là, ti òn ti ìmúláradá ní ìyẹ́-apá rẹ, fún ẹ̀nyin tí ó bẹ̀rù orúkọ mi; ẹ̀nyin ó sì jáde lọ, ẹ̀nyin ó sì ma dàgbà bí àwọn ẹgbọrọ̀ màlú inú agbo.

**Isàíàh 33:2:** Olúwa, ṣànú fún wa; àwa ti dúró dè Ọ́: Ìwọ ma ṣe apá wọn lí oròwúrọ̀, àní ìgbàlà wa nígbà ìpọ́njú.

**Isàíàh 40:1:** Ẹ tu ènìyàn mi nínú, ẹ tù wọ́n nínú, ni Ọlọ́run nyín wí.

**Isàíàh 53:5:** Ṣùgbọ́n a ṣa a lí ọgbẹ́ nítorí ìrékọjá wa, a pá á lí ara nítorí aìṣedédé wa; inà alàfíà wá wà lára rẹ̀, àti nípa inà rẹ̀ li a fi mú wa lára dá.

**Núméri 13:30:** Kálébù sì pa àwọn ènìyàn lẹ́nu mọ́ níwájú Mósè, ó sì wípé, Ẹ jẹ́ kí a gòkè lọ lẹ́kàn, kí a sì gbà á; nítorípé àwa lè ṣẹ ẹ.
**Orin Dáfídì 118:24:** Èyí li ọjọ́ tí Olúwa da: àwa ó ma yọ̀, inú wa yóò sì ma dùn nínú rẹ.

## ÀDÚRÀ SÓRÍ OMI

1. Bàbá mi, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún ṣíṣẹ̀dá omi gẹ́gẹ́ bí ara àgbékalẹ̀ iṣẹ̀dá adìtú Rẹ. Olúwa, Ẹ ṣeun nítorí omi jẹ́ ààmí àpẹrẹ Ẹ̀mí Mímọ́. Omi n fọ̀ nkan, ó n sọjí, ó n tẹ́nilọ́rùn, ó n sọdọ̀tun, ó n mú dúró, ó n ṣe iwẹ̀nùmọ́, ó sì tún jẹ́ amú nkan dàgbà.
2. Olúwa, dìde nípa agbára Àjínde Rẹ, kí O sì mí èmí Rẹ sórí àkójọpọ̀ omi yî. Jẹ́ kí iná Ẹ̀mí Mímọ́ ṣíji bo omi yìí, kí O sì sọ ọ́ di iwòsàn atòkèwá, omi iṣẹ̀dá, omi tó n rún ẹ̀mí òkùnkùn wómú-wómú, ajíra atòkèwá àti egbòògi aporó atòkèwá, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá mi, jẹ́ kí ohun gbogbo tó n bẹ nínú omi yìí gbé iná tíkò ṣe é pa, èyí tí yóò dójútì gbogbo irúgbìn òkùnkùn nínú ẹ̀jẹ̀ mi àti ní gbogbo àgọ́ ara mi pátápátá, jẹ́ kí ó pèníjà gbogbo májèlé tó farasin nínú ara mi, kí o sì tì í jáde, ní orúkọ Jésù.
4. Bàbá Olúwa, bí n ó ṣe mu omi yìí, jẹ́ kí agbára omi ìyè dàpọ̀ mọ ọ, sì jẹ́ kí ó sọ ìgbà èwe mi di ọ̀tun bí ti idì, jẹ́ kí ẹ̀mí ọgbọ́n, ẹ̀mí òye, ẹ̀mí imọ̀ràn àti ẹ̀mí ipá, ẹ̀mí ìmọ̀, àti ẹ̀mí ibẹ̀rù Olúwa bàlé ayé mi, ní orúkọ Jésù
5. Olúwa, bí n ó ṣe mu omi yìí, jẹ́ kí ó fọ gbogbo ìrúgbìn òkùnkùn kúrò nínú ayé mi, si jẹ̀ kí ó nù dànù ibànújẹ́ àti omi ìkorò tó n dàmú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
6. Agbárákágbara tó n tako ètò àti ipìnnu atòkèwá Ọlọ́run fún ayé mi, di ṣíṣí dànù nípa omi iná yìí, ní orúkọ Jésù.

7. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí omi yìí tú gbogbo ìwo òkùnkùn tí wọ́n gbìn lòdì sí ayé mi ká, jẹ́ kí ó pa gbogbo pẹpẹ tí wọ́n gbé kalẹ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi ní àyíká mi run, ní orúkọ Jésù.
8. Ìwọ omi yìí, wẹ aìsàn, àmódi, aìlèra àti àrùn tító dójú ikú jáde kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
9. Ẹ̀yà ara ìyówù tóti dòkú nínú àgọ́ ara mi, gba ìyè nígbà tí o ba á bá omí iná yìí pàdé, ní orúkọ Jésù.
10. Bàbá, jẹ́ kí omi iná yìí tú ìwà ìkà olóríkunkun àti àjẹ́ olóríkunkun nínú àgbègbè mi ká, ní orúkọ Jésù.
11. Agbára Jèhófà, rú omi yìí, kí o sì sọ ọ́ di omi tó n run ẹ̀mí òkùnkùn jégé-jégé, ní orúkọ Jésù.
12. Ìwọ to sọ omi Márà di adùn, sọ omi yìí di egbòògi aporó àti ajíra atòkèwá, ní orúkọ Jésù.